# IROHIN IMOLẸ

IMOLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 609 WEDNESDAY MAY 20, 1964 (2D)

## Ọwọ Tẹ Ole Ti Nṣọ Onile Pe Ki O Sun!

IBADAN:— Gbogbo awọn ero ti o wa ninu ile ẹjọ kekere kan ni nwọn rẹrin arin la omi lẹju nigbati awọn Ọlọpa mu Ọdaran kan, David Bamishe wa siwaju adajọ fun ẹsun igbero lati jale ati ija ti Ọdaran na si sare jade ninu apoti ti o dọbalẹ gbalaja ninu ile ẹjọ na ni ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi.

Ẹsun ti awọn Ọlọpa ka si Ọdaran na lẹsẹ ni pe, Ọdaran na lọ si Mọkọla ni deede agogo mejila abọ oru, o si lọ joko si ẹgbẹ kan, o sọ onile pe ki o sun ki on to bẹrẹ iṣẹ, ko mọ pe awọn enia wa ti o nṣọ ile na.

Ko pẹ ti o joko, ni ẹniti o nṣọ ile na ba ri i ti o si bi i lere pe, "Kini o nṣe nibi ni asiko yi?" Ṣugbọn bi oluṣọ ile na ti dakẹ ibere rẹ ni Ọdaran na ba gba a leti pe, "Iru ibere wo lo mbi mi.

Ninu ẹjọ ti Ọdaran na ro lati fi gba ara rẹ silẹ, o ni baba oluṣọ na ko bi on lere, ada lo yọ si on ti o si nle on lọ, o ni on joko lati gba atẹgun ni asiko na ni.

Adajọ ni ki Ọdaran na lọ fi pọnun mẹwa tanran si kotu tabi ki o lọ fi ẹwọn oṣu meji jura.

# IJỌBA HA ṢETAN LATI DIBO NI IWỌ ORUN BI?

IBADAN:— A ngbọ hunnu-hunnu labẹlẹ wipe, gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu ni Naijiria ni nwọn ti ngmura silẹ nisisiyi ti awọn ọmọ ẹgbẹ miran ti nra m ọ t o "kia-kia" ti nwọn o ma a fi polowo ibo atundi si Ile Igbimọ Asofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Oniwe irohin wa Ijon-'gboro ti O lọ si Ibadan ni ibẹrẹ Ọsẹ yi fi ye wa pe, gbogbo awọn ọ m ọ ẹgbẹ Oṣelu ti mura silẹ tan fun ibo atundi na.

O tun ṣe alaye siwaju pe, o fẹrẹ to Bọọsi kia-kia mẹjọ ti iṣe ti awọn ọmọ ẹgbẹ D ẹ m ọ (NNDP) ti ra on ri ni Ibẹrẹ Ọsẹ yi.

Bakanna ẹwẹ, ni on ri awọn mọto ti awọn ẹgbẹ Alakukọ fẹ ma a fi polowo ibo yika gbogbo Ipinlẹ na nigbati asiko ba to, ṣugbọn g ẹ g ẹ b i ipalẹmọ awọn ọmọ ẹgbẹ na ti Ejo-



Alhaji D. S. Adegbenro

n'gboro ri ni ibẹrẹ ọsẹ yi, fi han wipe asiko ibo na ku si dẹdẹ, ko si ni pẹ pupọ mọ.

Ṣugbọn bi Ijọba ti o wa lori aga ijoko ni Ipinlẹ na ti ngmura silẹ fun ibo na to nwọn nsọ fun gbogbo aiye gbọ pe Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ko ti ṣe tan ti yio tu ile Igbimọ Ipinlẹ na ka.

Gẹgẹbi alaye ti oniwe irohin wa ṣe fun wa lana, o fiye wa pe, Ijọba fẹ tu ile Igbimọ ka lojiji ati lairotẹlẹ ki ibo na o le ba gbogbo awọn enia ni ojiji.

### ẸGBẸ ALAKUKỌ

Ṣugbọn gbogbo bi Ijọba ti nṣe ni awọn enia na nsọ Ijọba lọwọ lẹsẹ ti nwọn si ngmura silẹ pe nigba yowu ti ipe na yio ba dun ki o ma ba ṣe ba ẹnikẹni ni airotẹlẹ.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na ti ke si gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ wọn ti nwọn wa yika origun mẹrẹrin Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria, pe ki nwọn maṣe fi gbogbo ara duro, nitoripe, lojiji ni ohun ipe na yio dun ki ohun ipe na ki o ma si ṣe dun ba ẹnikẹni lairotẹlẹ.

Awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ (N.C.N.C) tun ṣe afikun ninu ikilọ na pe ohunkohun lo le ṣẹlẹ lati igba yi lọ nitori ọrọ ti awọn ngbọ ni abẹlẹ pe, "Oloye S. L. Akintọla npete lati ju okete silẹ ki o si kuro ni Ipinlẹ na laipẹ."

Agbọrọsọ awọn ọmọ ẹgbẹ na ba oniwe irohin wa sọrọ ni Ibadan lana pe, "isọ inu ẹku arunmara ni edeaiyede ti o ti bẹ silẹ ninu ẹgbẹ Dẹmọ nisisiyi, ohunti o si fa ija na ni ẹniti yio gba ipo Oloye Akintọla nigbati o ba fi Ipinlẹ na silẹ"

Gẹgẹbi alaye ti ọmọ ẹgbẹ na ṣe fun oniwe irohin wa.



Dọkita M.I Okpara.



Oloye FANI - KAYỌDE



Oloye S. L. Akintọla

ni Ibadan lana, o sọ pe awọn ọmọ ẹhin Oloye Fani Kayọde, Igbakeji Alakoso Ijọba, fẹ ki Oloye na bọsi aye Alakoso Ijọba (Akintọla) ti oloye na ba le fi aye rẹ silẹ gẹgẹbi awọn ti ngbọ ni abẹlẹ.

Agbọrọsọ awọn ọmọ ẹgbẹ na tun ṣe alaye siwaju ninu ọrọ rẹ pe, o da on loju to ada, ti awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ba fi ja oloye Fani-Kayọde kulẹ, ti nwọn ko si jẹki o bọsi aye ti Akintọla fẹ fi silẹ, oloye Fani-Kayọde yio tu Ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ka, yio si pe fun ibo atundi ni Ipinlẹ na.

Ṣugbọn ti awọn ọmọ ẹgbẹ na ba fi gba pẹlu irọworọṣẹ pe ki oloye Fani-Kayọde o bọsi aye na, a jẹ pe, nwọn le ma tu Ile Igbi na ka siwaju asiko ti nwọn gbọdọ tuka.

Agbọrọsọ awọn ọmọ ẹgbẹ na tun sọ fun oniwe irohin wa pe, "Nwọn ti bẹ rẹsi i ko gbogbo ẹru oloye Akintọla kuro ni Ibadan nisisiyi.

"Awọn si gbọ pe, Apapọ Ijoba Ipinlẹ Ijọba Naijiria fẹ lọ fi ṣe Aṣoju Apapọ Ijọba Naijiria ni ilẹ awọn Jamani."

WO OJU EWE KẸFA

# ITAN AJIRAN ILU AWỌN OKU ( Apa 7 )

**Lati Ọwọ J. O. Shoyinka**

Nibiti mo ba itan migde lana ni yi. Ema ka lọ

Ti Ọba yi ba nrin lọ tabi ti oba joko a ma a nikan da sọrọ bi were. Ara Ayaba ko gba mọ, nigbati ori biọkọ on ti ndamu, o nwa ọna lati li tuu ninu, ni ajindun dundun ọjọ kan' odide lori ibusun rẹ o lọ ba Ọba nibiti oti nyan ho o toripe ko sun

O rọra fi irẹlẹ sun mọ ọ jẹ ẹ, o bẹrẹ si wasu fun un osi nṣe alaye lorişirişi fun ohun buruu ti oti sẹlẹ si awọn ẹlomiran, ti nwọn si ti bọ ninu rẹ. Nigbati ayaba bẹrẹsi ba Ọba sọrọ, iye rẹ si nsọbọ diẹdiẹ toripe ọjọ jọjọ ni'ronu ti dori rẹ kodo Ayaba na isọ bayi pe-:

Kabiyesi, Alayelu wa' ala şẹ ekeji orişa, on ti a fi pitan, ile Aiye la oba ko si nkan ti oju ko riri. Ti ibi ti ire lo orin papọ nile Aiye ọkọ mi olufẹ mi iwọ nikanşoşo ni mo fẹran ju laiye

Atoke ati isalẹ mi tirẹ ni işe ngo ha ba ọ sọrọ kan ki o kọ simi lẹnu bi Ninu aiye lati ri olowo to di talaka. Ninu aiye yi kanna lati ri talaka to di olowo, L'aiye yi kanna lati ri Ọba to dẹru L'aiye yi ẹwẹ lati tun ri ọba tod'ẹru to si tun d'ominira Adifa ilu ti sọ otitọ ọrọ fun wa ko yẹ ki o fi ẹtẹ silẹ ki o ma pa lapalapa ọkọ mi ọwọn ọrọ ironu kọ ni eleyi

Ọba jẹ tete yọnda fun ogboju le ogun ki o gbe ọmọ wani Iyawo gẹgẹbi adifa ti wi Ibatu, iba ba, iba dun ju oyin lọ. Ogun to mbọ ko ba si tilẹ ko ilu wa. Bi oti nsọ ọrọ yi ọkan Ọba ti bẹrẹ si tuka, o si gba ọrọ iyawo rẹ gbọ

Nigbati ilẹ mọ, Ọba pe awọn ẹbi rẹ jọ, ati ọmọde ati agba ati oyun inu, ti pesẹ sẹgẹ sẹgẹ lọjọ na nwon ko mọ ohun ti Ọba fẹ sọ, ọpọlọpọ nrope boya ofẹ ku ni, tori pe ọjọ ori rẹ ko mọ niwọn, tabi pe o fẹ şe eto



Ọgbẹni J. O. Shoyinka

ati pin ogun rẹ, abakiamọ ni gbogbo nwọn nşe.

kaban ni Ọba dide, o ki gbogbo ẹbi rẹ, oni ohun ti ohun fẹ sọ ko pọ. Atipe ohun rere ni. Inu awọn ẹbi rẹ dun nigbati nwọn gbọ bẹ Ọba wa bẹrẹ si sọrọ oni lagbara Ọlọrun on yio' fa ọmọ on fọkọ ni ọtunla orukọ ọkọ rẹ na a ma jẹ Ogboju le ogun - sọmọ - Ajẹni-ko.

Ẹnu ya awọn ẹbi Ọba, gbogbo wọn kun lọ hun un, nwọn bẹrẹ si wo ara wọn loju-toripe nwon ko mọpe Ọba le fi ọmọ bibi inu rẹ fun iru enia bẹ ẹ lọgan ni Ọba ti paa laşẹ ipe ki nwọn tun gbogbo agbala on şe. Inu ọmọ Ọba dun tobẹ gẹ ẹ, ti ofi jẹ pe ati sun di işe, o nronu igbaladdun alẹ ọjọ ti nwọn yio fa on f'ọkọ. (Ẹyin onkawe mi mọ pe "Alẹ ni alẹ ọjọ na yio jẹ nigbati apọn ọkunrin ba f'oju kan Wundia, gbugburu ati ẹpa yio ta.)

Nwon ti pa malu rẹpẹtẹ ni agbala Ọba, nwọn nse, nwọn nsọ, gangan, şẹkẹrẹ, aro, juju, kete, apala ati gbẹdu gba agbala Ọba kan, ni gbogbo rẹ ndun yingba. Awọn onibara ibẹ şeile, lalẹ arọ ni nwọn njẹun nibẹ.

Ọjọ pe Ọba ati Iyawo rẹ gun wa, nwọn ti wọ aşọ fun ọmọ Ọba on reti ọkọ rẹ Nko le şai şe alaye iru aşọ ti ọmọ Ọba na wọ:— Ọmọ ọba binrin yi ro gẹgẹ o gba gẹgẹ o wa le tentebi oşupa oju ọrun. oro aşọ sanyan o pele alari, o wegele sanyan da mẹtu, ohun ti ofi şe buba funfun nini-ni bi ẹgbon-owu, oyan re le te-te-te, onda okunrin lọrun, ọpẹlọpẹ awọtẹlẹ ni o jeki o fara-sin.

Idẹ Golu ati Ilẹkẹ ni nwọn fi şe bata ti o wọ. Ni kukuru riri ati wiwo rẹ da ti Angẹli awọn Wundia ti nwọn şe ọmọ iyawo rẹ lọ rẹpẹtẹ.

Gẹgẹbi mo ti sọ tẹlẹ ri, Ogboju-le-ogun paapa dara ni ọmọkunrin, ẹwa rẹ yi, ni o mu ọmọ Ọba ti ọkan rẹ fi fa si i lati fẹ ẹ. Gẹgẹbi ẹnyin na ti mọ pe, ireke ni Ogboju le ogun wa ta lọja ki ọmọ ẹran to de igba. (Toto o şe bi owe)

Ilu Ajiran ni o nlọ ki o to ba ọmobinrin yi pade, ko si ni ẹlomiran ju awọn ẹgbọn rẹ lọ. Eyi bẹrẹsi kọ ọ lominu, oju si nda ti i tori pe ko ri ẹni ba on lọ si ibi iyawo on ju ẹni mẹta lọ, on paapa şe ikẹrin. Bi o ti nro sihin, ro sọhun ni iranşẹ Ọba de, o jişẹ fun un pe nwọn nreti rẹ fun ti igbeyawo, o ni on mbọ.

Ko si aşọ, ko si ẹwu a fi apẹtẹ ati kijipa ẹwu ọdẹ rẹ ko si si aşọ lara awọn ẹgbọn rẹ pẹlu. Njẹ ko ha jẹ nkan itiju pe ki a fun ni lọmọ tan, ki a tun fun ni laşọ igbeyawo ? Nwọn nbi ara wọn bẹ ẹ.

Nwọn ta a ti nwọn ko mọ ọna ti nwọn le gba, ojo gẹngẹ tiẹ lẹ, ajagun bi akura ti işe ọkan ninu awọn arakunrin Ogboju le ogun wa bẹrẹsi sọrọ bayi pe:-

"Iwọ Ogboju—le—ogun ọkunrin daindain, mo şebi oti şe akapo Arọni ri?" "O si ti ba awọn iwin ati awọn irun malẹ gbe ninu igbo fun ẹdun jọjọ-nwọn gbọ ede rẹ, o si gbọ tiwọn ninu ogun nini, iwọ ko kẹ rẹ, o to gẹ ẹ ki o pe awọn irunmalẹ inu igbo toke ati ti isalẹ ẹmi ki nwọn sowopọ lati lọ bawa şe aşeyẹ ni.

Iye rẹ sọ kiji o bẹrẹ si jẹ ata're, o npọfọ, o nfi orişirişi ede ti ẹda ko gbọ pe awọn alujannu şugbọn nwọn ko yọ si i o ku wakati kan pere Ọba tun ranşẹ wa.

Ara ọmọ Ọba ko balẹ nitoripe o ti fẹran Ogboju-le-ogun ju ẹnikẹni lọ. Ẹru si mba a pe ki o ma ba ti sa lọ. Şugbọn nigbati ikọ jişẹ fun Ọba pe o mbọ. ọkan Ọba ati ọmọ rẹ balẹ, toripe ti ti o ba fi bẹ lọ. itiju nlanla ni yio jẹ fun Ọba ati idile rẹ laisiani-ani ọmọ-Ọba ko si kọ lati pa ara rẹ



Aworan Oke yi ni ti Ajiran Ilu Awọn Oku

GET THE WATCH WITH PERSONAL TOUCH
WITH YOUR PHOTO REPRODUCED ON THE DIAL
A fortnight after receipt of your photo we will send you a Windsor watch with lifetime guarantee
Réf. N° 55. PHOTO
Free illustrated catalogue on demand

A Wonderful 15 Jewel lever shock protected, movement, non magnetic, unbreakable mainspring ROLLED GOLD waterproof case and stainless steel back with your name engraved.
Beautiful diamond polish raised figures, luminous and YOUR PHOTO reproduced IN COLOR on metal dial.
PRICE £ 5.
HURRY SEND YOUR PHOTO (any size) with cash or cheque
WINDSOR
19, Avenue de Lérins - Cannes, France

# IWE SI OLOTU

## Ọra Igbomina Nfẹ Atunṣe

Inu mi yio dun bi Olotu ba le gba mi ni aye ninu iwe nyin ti nkọwa ni ọgbọn ati oye lati kesi Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria pe ki nwọn ki o tete ba wa tun ilu wa ṣe ni asiko yi, ilu wa nfẹ iranlọwọ Ijọba. Ati nkesi Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ti rẹ pe, ki wọn ki o le tete ba wa tun ilu wa ṣe bi awọn ilu miran.

Inu wa nfẹ ina manamana ti a o mọ lo bi awọn ilu nla bi Ibadan, Eko ati awọn ilu lanla miran ni Ipinlẹ Iwọ-Orun, epo pupa su wa ni lilo, awọn Ọmọ wa ko n'i ina to dara ka iwe wọn bi awọn enia ilu nla yoku.

A tuu nfẹ Ile-Isepade fun ilu wa, bi a ba fẹ ṣe ipade ni ilu wa a ki ri aye rara, a fi ile-Ọlọrun ni aye wa, nitorina mo nbẹ ẹnyin Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun pe ki ẹ ran.

Ilu wa nfẹ iranlọwọ Ijọba o ti pẹ, a si fẹ ki ẹ ba wa tun ilu wa ṣe bi awọn ilu nla miran ni Ipinlẹ Iwọ-Orun Ẹ iọwọ, ẹ ba wa tun ilu wa ṣe.

Olotu asiri yin yio bo o, aṣẹ

Emi ni

D. A. Ibitoye

ỌRA-IGBOMINA.

## Ti Ọkpara Ti Jẹ?

Nba sọpẹ bi Olotu Iwe Irohin Imọlẹ ba le gba mi ni aye ranpẹ ninu iwe rẹ Oloyin mọmọ lati ba awọn ọmọ Yoruba sọrọ, nitoripe ẹniti a bi wọn bi ko'nwu wọn ẹni ẹlẹni ni oya wọn lara ni gbogbo ọran ilẹ Yoruba jẹ ni asiko ti a ıa yi.

Bi eleyi yio ba sọrọ, ani Dọkita Ọkpara ko ni gba igbejade enia kika, bi ti ọhun yio wi ọkanna ni on na yio wi pẹlu, ko wa si ẹniti ole tako igbejade enia kika afi Dọkita Okpara nikan.

Ọrọ mimọ Ọlọrun ni ki a mọ



Dokita Okpara

ṣe tan nyin jẹ enia ko le kẹgan Ọlọrun, ohun kohun ti enia ba furugbin ni yio ka, Ojẹ awa pe ẹnikan yio ko abajade enia kika

Nigbati nwọn ka ni Idun ta nwọn ni ẹburu wọ awọn ti o ka tesin yato patapata awọn ọmọ Ile ati ti Yoruba ni o lọ ka ti Ipinlẹ Ariwa, ko ba ye nyin, ẹ lọ ke si awọn Ibo ati Yoruba ti olo ka ki nwọn fun yin ni isiro bi nwọn ti ṣe ka wọn.

Ẹ ma tan arayin jẹ mọ, ọrọ enia kika ti pari patapata, ẹ mọ tan wa jẹ mọ, ọrọ enia kika ko si okunkun fun arawa,

Olotu mo dupẹ aye ti ẹ gba mi,

Emi ni

Kikẹl,mọ Ajẹo
YABA

## A Nfẹ Ibo

Ẹ dakun ẹ gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin ti nkọ wa ni ọgbọn ati oye lati ba Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun sọrọ, nitoripe ipo ti Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria wa nisisiyi ko dara to rara o si nfẹ atunṣe gidi

Gbogbo Ipinlẹ na ti daru. a ko si mọ ibiti a nlọ mọ Ijọba ti owa lode yi ko ye wa rara gbogbo rẹwa di rudurudu, Ipinlẹ na dorikodo a ko mọ ẹgbẹ ti ao ṣe mọ ni nu awọn ẹgbe onṣelu.

Ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Alakukọ ni a mọ ni Ipinlẹ Iwọ Orun awọn ẹgbẹ na ni a şi mọ di ibo fun n' gbakugba ti ibo didi ba waiye ni Ipinlẹ na'



Oloye S. L' AKINTỌLA

A maẹgbẹ U. P P ko ye wa si rara, a da ẹgbẹ na silẹ lai pẹ Ọdun melokan atun ni ẹgbẹ na ko dara mọ ẹgbẹ Macaulay ti ojẹ Dẹmọ ni otun le mu sọkan wa si arin awaYoruba.

Ibo didi ni ole mu isọkan wa fun gbogbo ọmọ Yoruba nigbana ni a wa mọnu odo ti ada ọrunla si. Ejọwọ a nfẹ ibo kiakia ki alafia ole wa ni Ipinlẹ Iwọ-Orun,

Emi ni

Samuel Arẹmu

Oṣhogbo


# EGBOGI JEDJEDI

BERE EGBOGI



## "CYCLOVEN'

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jẹdijẹdi rẹ gbe wa lara rẹ si nyọ ọ lẹnu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu tabi Iho idi enia ibiti a ma ngbe ṣe igbọnsẹ. Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni patuki fun Ọkunrin ti o si lagbara pupọ lati ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri lode nisiyi ti wọn a ma po owo wọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya la leri mẹwa ninu ọgọrun ti o le ṣe iwosan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe boya bi wọn ba lọ si ile Dokita lati lọ ke eyiti o ba nyọ jade lati omusu ku ni pa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata.

Ṣugbọn awa ko ro bẹ rara. Lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun bẹrẹ bakana. Orişirişi Jẹdijẹdi ni o wa ekini ti o bẹrẹ nipa aiko mọ ṣe igbọnsẹ dede tabi lojojumọ, ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna pẹlu lojoujmọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ẹwẹ nipa jijẹ Ṣuga tabi oniruru ohun adidun pupọju nigbakugba. Jẹdijẹdi orişirişi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ ade ninu omusu, tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnsẹ, tabi ti o ba nyọ ti o ba ṣe igbọnṣẹ tan ni, tabi ti nrin ọ ninu omusu ni eyikeyi ti o ba ra bere egboogi, "CYCLOVEN" ti awọn Oyinbo Jamani ṣẹṣẹ wa idi rẹ kio si panwo orişi mẹta ni o daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijedi patapata alafia yio de si ekeji rẹ ko si ninu gbogbo egbogi tasboro Naijiria jakejado. Bere rẹ ni:

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji)

## Iyipada Ile Isẹ

Eyi nilati kede fun awọn Onibara wa pe ati ko ile itaja wa kuro ni Ibadan patapata asi ti wa si Ilu Itirẹ ni Agbegbe Suru Lere ati Mushin.

Ẹnikẹni ti o ba fẹ bawa ra Iwe tabi Turari Ajẹbidan ki o wa si ile itaja wa ni Nọmba 1, Ishiba Street Odo Eran Itirẹ

## Apejuwe Ile Isẹ Wa

Ẹ Wọ Bọọsi ti o nlọ si Lawanson ni Yaba 3d pere ti oba sokalẹ ni Lawanson, bere Ilu Itirẹ. Ti o ba de Ilu Itirẹ bere ibiti nwọn ti npa malu, titi ibẹ ni itawe wa wa Ti o ba fẹ fi owo ransẹ fun ọja rẹ Adirẹsi mi niyi:-

Shoyinka
c/o Postal Agent,
Itirẹ Via,
Suru Lere, Yaba

AWỌN IWE TI O WA FUN TITA

| | |
|---|---|
| Iwe Egbogi Awo Igba Arun | 20/- |
| Iwe Egbogi Ajẹbidan | 25/- |
| Iwe Ala lati ọwọ Josẹfu Alala | 5/- |
| Itumọ Ami Ara ati Etutu | 20/- |
| Iwe Ilana Yanrin titẹ ati Etutu Ṣişe | |
| Iwe Afọsẹ Isẹdalẹ Yoruba ati psalmu Ajẹbidan | 4/- |
| Lilo ati Agbara psalmu | 7/- |
| Turari Işẹgun Ajẹ ati Adura Tete damilohun | 10/6 |
| Iwe Akọmọ Lesin Islam ati Orisirisi Iwe | 1/- |

J.O. Shoyinka
c/o Postal Agen
Itirẹ Via Suru Lere,
Yaba.

or 1,Ishiba Street (Odo Ẹran)
ITIRẸ

# Fani-kayode Tu Ijọba Ibilẹ Mẹwa Ka

IBADAN:— Igbakeji Olotu ipinlẹ Iwọ Orun ati alakoso Ijọba ibilẹ ni Ipinlẹ iwọ Orun Oloye Remi Fani-Kayode ton tu mẹta ninu igbimọ adele ijọba ibilẹ ipinlẹ iwọ Orun Naijiria ni agbegbe mẹwa ni Ipinlẹ Iwọ Orun

Awọn agbegbe mẹta na ni Ẹgbado, Okitipupa ati Ondo.

Ninu waya ti Oloye Fani-Kayode fi ranṣẹ si awọn



Oloye FANI—KAYODE

Ijọba ibilẹ marun to tu ka ni agbegbe Egbado, o si sọ sinu waya na pe Olufoshan to wa ni agbegbe Egbado,

Ọgbẹni A. Ekefre pe nwọn ṣ ti yan gẹgẹbi Alakoso ti yio ni Ijọba ibilẹ marun ti o wa ni agbegbena

Iru waya bẹ ni igbakeji Olotu Ipilẹ Iwọ-Orun Naijiria si ti fi ranṣẹ si awọn ijọba ibilẹ ni agbegbe Okitipupa awọn Ijọba ibilẹ na ni Ikalẹ Idapọ marun, Ikale Orisun mẹta ati Ijọba ibilẹ ti iha Gusu ti ẹkun Ondo

Ninu ọrọ ti awọn alakoso ile iṣẹ ti nṣe akoso ijọba bilẹ ni Ibadan fi ye oniroyin wa pe nwọn ko ni yio adele kankan si awọn ile igbimọ Ijọba ibilẹ ti nwọn tuka titi nwọn yio fi dibo si awọn ile igbimọ ijọba ibilẹ ti Ipinlẹ Iwọ-Orun ninu ọdun yi.

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AGUARIUS:- (Jan 22-Feb 20) Ọkan rẹ kun nisisi yi to bẹ ti iwọ ko mọ eyiti iwọ yio ṣe, o to akoko ti o ni lati wa okodoro ọrọ na nipa ọrọ rere ni iwọ le pari edekoyede kan ti o ti mbẹ nilẹ fun ọjọ pipẹ.

PISCES:- (Feb 21-Mar 20) Ole ba ọrẹ rẹ kan obinrin sere konigbagbe ki o maṣe jẹki aiya rẹ ja mọ'

ARIES:- (Mar 21-April 20) Maṣe fi ọkan si nkan ti o nṣe ninu ẹgbe kan lọwọ nitoripe ko nṣe ẹgbẹ to ni lati ki o si ṣọra rẹ ni alẹ oni ewu mbẹ fun ọ lọdọ obinrin.

TAURUS;- (April 21-May 20) Ojowu ni ọ ṣora rẹ ki o le jẹki awọn enia ni igbẹkẹle si ọ ki o si ṣọra rẹ ki o maṣe jẹki ọrọ buruku ti ẹnu rẹ jade ni alẹ oni.

GEMINI:- (May 21-June 21) Maṣe gbagbe obun ti o mọ jẹ ọgbọn ori rẹ yio se ọ ni oge loni yio si jẹki o ri ere nla je.

CANCER;- (June 22 July 23) Ohun ti iwọ yio ba ṣe se e ni ọkọkan pelu ironu ṣe si ru ki o si sọra nipa sisọ ọrọ ti ko ni tan ni owurọ yi, I hin ti o ba sun ti o si ji, ọmọluwabi ni ki o ma ba ko ẹgbẹ.

LEO (July 24 Aug 22) Awọn to nṣe iranlọwọ fun ọ yio da duro loni, bi o ri aye rẹ ki o tun gba oniranlọwọ miran.

VIRGO (Aug 23 Sept 23) Ẹnikan ti o jẹ ọrẹ rẹ yio ni egbọn ti o peye, maṣe jafara lati rin sun mọ ọ ni na, iṣẹ ọwọ rẹ dara, mura ati lo o

LIBRA (Sept 24-Oct 23) Gbogbo iṣesi ati ilosi rẹ lo ti orire gbogbo inawo rẹ, logun, awọn ojulumọ rẹ ni yio di igi ẹhin ọgba fun ọ.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Maṣe lero pe ọti mimu jẹ ohun to dara fun ọ ki o ṣọra rẹ nipa nkan mimu ki o ma ba nu ohun ti ko ni se o ni anfani.

SAGITTARIUS (Nov 23- Dec 22) Ita arisiki rẹ ti tan, ohun kihun ti o ba si de, agbara mbẹ fun ọ lati ṣẹgun iṣoro gbogbo, maṣe bẹru bi ọkunrin alagbara ba nyọ ọ lenu iwọ yio bori.

CAPRICORN (Dec 23-Jan 23) Ẹwa oju dan, oju rẹ nwu gbogbo enia, nwọn si afẹ ki o ma ba wọn ṣere ṣugbọn ṣọra ki o maṣe jẹ ẹran titu pupọ, nitori ewu mbẹ ninu rẹ

BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARAN TI NWỌN NPE NI - Eleyi yatọ patapata si awọn

# RICHALẸT

FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO

Robi-robi. Iṣẹ rẹ lara enia ju da si fun Iwosan gbogbo Kokoro buburu ti o ba wa ninu ẸJẸ ARA' bi Monamona,




Mejì rẹ ko si ni gbogbo awọn Egogi ti nwọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti awọn si ni kakiri ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo Iyẹn ṣe ewọ, awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npo ta ni lẹ yi,

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ iruẹ awọn egbogi ba wọn yen a ma a ba ojulowo egbogi atata ti a ranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati ti awọn Latombulu si Itali jẹ

Mọ daju pe, bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi aijera wọnyi le se ọ, Lakuregbe, orisirisi Inarun, Oju ṣuṣu tabi didun Jẹdijẹdi Akọba, arun Edọki, Aya - didun pupọ ati ikuru laya

Ara riro, lapalapa Egbogi-Amodi Apo ile ilọ, ẹhin didun tabi baradi rira pelu Egbogi RISALETI a ma a pa gbogbo kokoro buruku ti o wa nba ẹjẹ ara rẹ patapata yio si ni ẹjẹ rẹ mọ toritoni pẹlu.

Ṣa dan igo rẹ kan wo iwọ yio si ma a rohin rẹ fun ẹlomi na pẹlu

Bere Ṣọbu awọn:—

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street (Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, Ọja Ita Faji)

ADEDUN CHEMIST
14. Wakeman Street Lagos
NIGERIAN MEDICINE STORE
Tinubu Square Lagos.

BI O BA NI

# Iwe—Titẹ

FUN

**Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orisirisi iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

**Iwe gbeyawo**

TETE KOWESI ILE—IṢE—ERO ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**

16 Bamgbose Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985. Lagos.

KETEKETE NI ERO ITEWE WA NHAN
OWO POKU NI A SI NGBA

IROHIN KO TO AFOJUBA

# Ọtẹlẹmuyẹ Nki Nyin o

Ọtẹlẹmuyẹ nki yin o, Ẹ ku owurọ ẹ si ku idaji, ṣe ara le o? Mo ki Olotu pe ABILARAN O ẹnyin alabaşişẹ pọ Irohin Imọlẹ mo bẹrẹ f'oji o.

Lati igbati mo ti ta awọn Woli eke ni ọfa, ni nwọn ti nsunkun s'oju kiri, eebu ikan ko jọ ikan ni nwọn mbu mi ni o de iwasu ti nwọn nṣe kakiri ilu.

Ṣugbọn mo dupẹ lọwọ Ọlọrun pe, gbogbo awon enia l'ọkunrin ati l'obinrin ẹhin mi ni wọn wa ti nwọn si nse adura fun mi pe, Ki emi mi gun lati ba ma a tu na aşiri wọn dọba.

Ọtẹlẹmuyẹ Pade Woli Eke Kan

Laipẹ yi ni mọọmọ lọ ba Woli kan ni ibuba rẹ ti o pe ni ṣọọsi, nigbati o gbadura fun mi tan, a jijọ wa bẹrẹsi fi ọrọ jomi toro mo ni, alagba ẹ ko ri pe "BILASIFẸMI" ni Ọtẹlẹmuyẹ nsọ nipa awọn Woli' Woli na si dahun pe, arakunrin mi nko fẹ ki o şi Ọtẹlẹmuyẹ gbọ rara nitoripe awọn Woli eke ni o nsọrọ nipa rẹ kii ṣe Woli Ọlọrun.

WOLI EKE NA SỌ OTITỌ

Woli na tun sọ siwaju bayi pe, ti Ọtẹlẹmuyẹ ni nsọ yẹwo, ti o ba di igba ti rẹ, ti o ba ri owo ki o ma gbo o. ti o ba si ri obinrin ti o jọju ninu Ijọ ki o ma fi şe aya o, Ma da lohun ti Ọtẹlẹmuyẹ ba wa gẹgẹbi Woli yio ṣe jubẹ lọ o jare. Fi ọrọ ti Ọtẹlẹmuyẹ silẹ ki o ba wa ohun ti ngo jẹ. Mo si sọ fun pe, Oluwa yio yọ ẹ o Woli. O rerin titi, oni ha! iru ọrọ wo ni mo sọ yi; njẹ enia le ma gbadura fun enia lasan lai jẹun ki oyi ma gbe lulẹ ni ọjọ kan.?

MO RẸRIN

Mo ku s'ẹrin, mo wa fi awọn ibere wọnyi siwaju rẹ mọ ni:

Ọtẹlẹmuyẹ: Ṣebi awọn Woli igbani aginju ni wọn ngbe, kiniṣe ti ẹnyin Woli aiye ode oni fi ngbe arin ilu?

Woli eke: Awọn Woli igbani ni yẹn tani yio gbe aginju igbo ki ejo tabi ẹranko buburu wa pa jẹ'

Ọtẹlẹmuyẹ Ṣebi agbara adu ra ni awọn Woli Igbani fi nle awọn ẹranko buburu jinna si wọn?

Woli eke: Iwo ko ri pe, awọn Woli igba mọ ajẹbi dan si ni adura wọn nitoripe Oluwa ntẹti siadura wọn.

Ọtẹlẹmuyẹ: Iyẹn ni pe, awọn Woli aiye ode oni ko mọ?

Woli eke: Ki i ṣe gbogbo wọn, ṣugbọn ọpọlọpọ ni ko mọ, panşaga ati oju kokoro owo, obinrin ko jẹki Oluwa gba adura wọn.

Ọtẹlẹmuyẹ: Inu mi dun pe ẹnyin ti ẹ jẹ Woli jẹri si nkan wọnyi.

Woli eke: Ẹ jọwọ alagba tabi ẹnyin ni Ọtẹlẹmuyẹ gan an nitoripe awọn ibere yin, mu mi fura si yin.

Ọtẹlẹmuyẹ: Emi kii ṣe Ọtẹlẹmuyẹ o, Ṣugbọn ọrọ rẹ ti mo nka ni gba gbogbo nipa awọn Woli eke ni o ṣe jẹki ngma bere awọn ọrọ na lọwọ yin Bayi ni mo ṣe rọra poora mọ lọwọ nigbati o fẹ fura si mi.

Njẹ ẹnyin onkawe mi ẹ o r'oju aiye tabi ẹ ko ri? ẹniti o ba ni eti lati fi gbọ ki o gbọ o, awọn Woli eke ti de ile aiye nisisiyi o, ẹ maşe jẹki nwọn tan yin Oluwa ki o wa pẹlu wa o Amin

ITIRẸ NFẸ AMOJUTO

Iha dara pupọ bi awọn Ọlọpa Mushin ati awọn Ọdẹ ba le jijọ fọwọsowọpọ gbogun ti awọn ole, ọlẹ ati igara ti nwọn wa ni Itirẹ. Idi Araba ni awọn ole wọnyi fi ṣe ibugbe tẹlẹ ri ki awọn ọlọpa to ti ọgbagbara bọ wọn ni idi, ki nwọn to wa di ero Itirẹ nisisisiyi.

ẸHIN IGA ỌBA

Ibi kan wa ni Itirẹ ti nwọn npe ni "Ẹhin Iga" ibẹ ni nwọn fi ṣe ibujoko nisisiyi ti nwọn si nda bira buruku onile ko gbọdọ fi ile rẹ silẹ lọsan. iṣẹju akan nwọn ti koo ni ile agaga oru iṣẹ ile fifọ ni nwọn nṣe ka kiri.

ALAPARA IBADAN TI KESI ỌLỌPA NIPA WỌN RI

Lati le kin ọrọ Alapara Ibadan lẹhin mo bẹ awọn ọlọpa Mushin ki nwọn bẹrẹ lati isisiyi lọ lati maa mu awọn ti nwọn nmu igba ra kiri laseko iṣẹ ti ẹba de adugbo ti mo wi yi ẹ o ri awọn gende Ọkunrin bọpabọpa ti nwọn nrin ... ṣe, ọna wo ni 'yio gba ri onjẹ oojọ rẹ jẹ? Ole jija ni.

IBOOSI I PA

Ẹ dakun ẹ bawa tojubọ awọn ole wọnyi lara, kalafia le to awọn olugbe Iti rẹ. Ẹ o tun maa gbọ ni pa awọn "AGBODEGBA" awọn obinrin jaguda bi nwọn ti ṣe ntan awọn ọkunrin si idẹkun ọkọ wọn.

Emi ni Ọtẹlẹmuyẹ atu wọn ka nibi nwọn gbe ndans Irọ nrele o. Ipade wa ti oyin o.

Kakiri ilu Itirẹ laseko ti awọn enia wa lẹnu iṣẹ. Mo bere o, ẹniti ori iṣẹ ti ko

## Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ipade gbogbo gbo o yio wa fun awọn ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Ayie ni ọjọ kẹrinlelogun oşu karun (24/5/64) ni deede agogo meji ọsan ni nọmba 16, Ba gbose Street Eko.

Ao si tun fi tayọtayọ gba awọn ọmọ ẹgbẹ titun ti nwọn ba wa si ipade lati jẹ ọmọ ẹgbẹ.

Ki ẹ tete de o

LATEEF BABALỌLA
Akọwe Agba



## Congreves Female Remedy

(FUN OBINRIN)

Ojulowo egbogi titun fun gbogbo awọn Obinrin boba ni iyọnu tabi amodi Inu rirun nigbakugba tabi ni ẹkọọkan ẹhin-didun, Ibadi-wiwo tabi sisan ẹjẹduda ara tabi aikoto ẹjẹ lara Inu gbigbona nigbakugba Igba — aiya riru ọmu riro, didun ara atinu wa ni o ma nfa oyi-oju Ilaogun ati ẹsẹ ara sisọn, efọri tabi pẹlu iba ati otutu Egbogi yi dara pupọ julọ fun itọju gbogbo Obinrin gẹgẹbi Ajo fun ilera ati orişirişi amodi miran ti o ma nyọ wọn lẹnu ni inu nigbakugba pẹlu.

(OLOMI IGO NLA NI)

BERE EGBOGI ATI IỌ TI WỌN NPE NI:-

### Ammoniated Quinine Tincture

Nigba lailai ki awọn Orişirişi rọbirọbi egbogi ti wọn ko wa nisisiyi to de awọn agbalagba aiye atijọ mọ daju wipe kosi ohun ti a le fi Iwe egbogi yi bi otutu ikọ iba, orẹrẹ lukuluku onigbameji tabi a i p e r i nyọ enia lẹnu yala Ọmọde tabi agbalagba ni ylo ṣe iwosan rẹ bi danga ni bi oba ti ta diẹ sinu omi ti o lọwọrọ ki o si gbemu bere egbogi ti o daju fun itọju eti riro tabi didun, ati Akokoro, egbogi ti o ma nfọ apo-ile-itọ tabi se iwosan iyọnu apo-ile-itọ egbogi oju didun tabi ti ọna-ọfun didun, ati orişirişi omiran pẹlu wọn mbẹ ni şọbu awọn :—

Waterloo Medicine Stores,
8, PalmChurch Street, Lagos.
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

ADEDUN CHEMIST
14. Wakeman Street Lagos

NIGERIAN MEDICINE STORE
Tinubu Square Lagos.

# IROHIN IMOLE

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 609 WEDNESDAY, MAY 20, 1964 (2D)


## Ọkọ Iyawo Kan Wẹwọn Oṣu Mẹfa

IBADAN:- Gbogbo ile kunṣoṣo ti ẹsẹ ko si gba ero fun Ogunlọgọ enia ti wọn wa sinu ile ẹjọ kekere Ibadan nigbati awọn Ọlọpa mu ọdaran kan, Frances Adejinwọn, ẹni Ọdun mẹdọgbọn wa siwaju adajọ fun ẹsun ole jija ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu yi.

Ọlọpa ti o ba ọdaran na ṣẹjọ ṣe alaye fun ile ẹjọ pe, Ọdaran na ji taya ẹsẹ mọto mẹta ti iye owo rẹ jẹ Pọnun mẹrindinladoje (£126 ) gbe ninu ile Iṣẹ awọn Olomi—ẹrọ "Water Resorses Development Limited Ibadan"

Ọlọpa na tun se alaye pe oṣu kẹfa niyi ti ọdaran na ṣẹṣẹ gbe iyawo ki Ọlọpa na to sọ bẹ tan ni gbogbo awọn ero inu Ile ẹjọ na mi ori ti wọn si pose

Siwaju si i Ọlọpa na tun fi ye ile ẹjọ pe ninu Osu karun Ọdun ti o koja yi ni ọdaran na ti gbe taya ẹsẹ Mọto na Nigbati awọn alaṣẹ ile iṣẹ na si wadi ọrọ na daada, nwọn ri pe Ọkunrin na ti gbe taya ẹsẹ mọto na. Nigbati ọdaran na rojọ ti o si gba pe onjẹbi ni adajọ ba ni ki o lọ si ẹwọn Osu mẹfa afarabara.

# MOTO AKERO KAN TAKITI SINU ODO OSHUN !!

### Enia Mẹta Ku Bamubamu. Mẹrindinlogun Fara Gbọgbẹ !

ILESHA: Jinnijinni dabo gbogbo enia nigbati mọto akero kan, nọmba WC 510 nko awọn ero kan lati Ilọrin ti o si de odo Ọshun larin Ilesha si Oshogbo ni mọto na ba takiti sinu odo Ọshun ti o pa enia mẹta ku bamubamu ti enia mẹrindinlogun si fi arapa lọpọlọpọ ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹdogun osu yi.

Oniwe irohin wa ni Ilesha ti o lọ sibi ijamba mọto na ṣe alaye fun wa pe, lati Ilọrin ni mọto akero na ti mbọ. Nigbati yio fi kuro ni Ilọrin, ẹja gbigbẹ, ẹran-ẹgbẹ ati apo ẹwa ni mọto na ko, ṣugbọn nigbati o de ibudo mọto ni Ilọrin ni o ba ri awọn ero kan ti nwọn ti nduro de mọto, nwọn si ju ọwọ si i pe, ki o duro

Nigbati mọto na duro, o sọ iye ti yio gba lọwọ awọn enia na de Ilesha, nigbati nwọn dunadura; ti adehun si bamu ni o ba ko gbogbo wọn sinu mọto rẹ.

Nigbati nwọn de Oshogbo mọto na duro awọn enia sọkalẹ, nwọn lọ ra nkanjẹ, awọn miran omimu awọn miran tọ, nwọn si tun wọ mọto na lati ma a lọ si Ilesha·

Sugbọn nigbati awọn mọto na de odo Ọshun ti o si fẹ sare kọja lori odo kereni Ọshun ni ọwọ ọrẹ ba taṣe kuro lori ọna, o si ko sinu odo Ọshun, eyiti o jin to ogun ẹsẹ bata.

Lẹsẹkẹsẹ ti awọn ara iieto ti o wa ni agbegbe na ati awọn ero ti o wa ni okere ati mọto na, ti nwọn, si gbọ agbayamu ariwo nla ni gbogbo wọn ba sare pe ti nwọn nkibosi.

Lojukanna ni nwọn ti sure lọ pe awọn ọkunrin wa ti awọn kan si ransẹ si awọn ọlọpa Oshogbo. Nigbati gbogbo wọn de, ariwo ibosi o! ni gbogbo wọn nke.

Ọlọmọ nwa ọmọ, onibaba nwa baba, Ọlọkọ nwa ọkọ, oniya nwa iya, ẹlẹbi nwa ẹbi, alaya nwa aya, ariwo, "ẹ gbani o, ao mọ ri iru eieyi ri o!" nigbogbo enia nke, ni ọjọ na.

Lẹsẹkẹsẹ ni awọn Ọlọpa ati awọn apẹja adugbo na ba sare ko sinu omi ni isalẹ ti nwọn si nlọ gbe awọn enia na wa ni ọkọọkan wa si oke, ṣugbọn enia mẹta lo ku bamubamu ti enia mẹrindinlogun si farapa.

Nibiti nwọn ti nwa awọn enia na ni nwọn ri ọmọbinrin kan ẹni ọdun mẹsan ti o lefo loju omi ti odo si ngbelọ, lẹsẹkesẹ ni nwọn gbe ọkọ si oju omi ti nwọn si sare lọ gbe ọmọ na ni nkan bi igba ẹsẹ bata si ibi ti ijamba na ti ṣẹlẹ.

Irohin fi ye wa pe, ẹran ẹgbẹ ti mọto na ko ti di ẹran tutu ati ẹwa on pẹlu ẹja gbigbẹ gbogbo wọn wa ninu mọto na, nwọn si nwa ọna lati yọ mọto na jade ṣugbọn, gbogbo awọn ti o ku ati awọn ti o farapa , ni awọn Ọlọpa ti gbe lọ si Ile iwosan Oshogbo.

Ki Oluwa gba wa lọwọ awọn awamọto sare o.

# Ijọba Ha Ṣetan Lati Dibo Bi?

LATI OJU EWE KINI

Agbọrọsọ na tun ṣe afikun pe, "Eko ni awọn gbọ pe, nwọn nko ẹru Oloye na lọ ninu ile rẹ ni Ajasa Street, ṣugbọn awọn ko ti mọ ọjọ ti Oloye Akintọla yio fi Ibadan silẹ, ṣugbọn ko ni pẹ pupọ"

Ninu ikede kan ti o jade ninu ile awọn Ọmọ ẹgbẹ na ni Ibadan lana, awọn Ọmọ ọgbẹ na ti kesi ẹgbẹ Dẹmọ pe, ki nwọn lọ da Ọkan ti awọn enia na pe ni "iwa aidara" ti awọn Ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ nhu duro si awọn Ọmọ ẹgbẹ Alakukọ,

Ikede na fi ye gbogbọ enia gbọ pe, adọta Ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ti o wa lẹnu iṣẹ ni Ijọba ti da duro lẹnu iṣẹ ni Ibadan. nitoripe, awọn enia na kọ lati faramọ ẹgbẹ Dẹmọ.

Nwọn ni, nigbati Ijọba ba fẹ kọwe si awọn Ọmọ ẹgbẹ na, nwọn a sọ pe, 'Ijọba fẹ ṣe atunṣe ninu ile iṣẹ, ẹ lọ joko sile fun igba diẹ, na, ao tun pe nyinti o ba ya."

Awọn Ọmọ ẹgbẹ na ni. Ohunti o wa ya awọn lẹnu ni pe. ti nwọn ba ti le awọn Ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ sọnu tan, lẹsẹkẹsẹ bi iṣẹju aya, ni nwọn o ti gba awọn Ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ rọpo wọn.

Ṣugbọn Ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ kan ti Oniwe Irohin wa ba pade ni Ọja Dugbẹ ni Ibadan lana sọ pe awọn gbọ wipe Dokita Okpara mbọ wa ṣe ibẹwo Ipinlẹ Iwọ Orun laipẹyi.

Ọmọ ẹgbẹ na sọ pe. ki Okpara ma ti ṣe ibẹwo wa si Ipinlẹ na nisisiyi, nitoripe ibẹwo rẹ le tun da rogbodiya silẹ larin awọn enia iru eyiti o ṣẹlẹ ni idunta.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na ni, rogbodiyan ti o ṣẹlẹ ni idunta ṣẹṣẹ fẹ kasẹ nilẹ ni, ọran rẹ ko si titan nilẹ.

Lati bi ọjọ mẹta ni ati ngbọ pe, Dọkita Nichael Okpara Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun Naijiria fẹ ṣe ibẹwo awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ yika Ipinlẹ na.

Awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ sọ pe, ọrọ abayọri eto ikania ni Dọkita Okpara fẹ ma ba awọn enia sọ.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na wa sọ pe, "Niti wa, eto abayọri ikania ti di ohun inigbagbe ti ko yẹ lati tun sọrọ nipa rẹ mọ, nitoripe ọrọ na dabi igbati enia nda epo si inu ti o ti ku ni ori loju awọn.

Ni ipari, awọn ọmọ ẹgbẹ na wa berepe, "Ṣebi Okpara ti pe Apapọ Ijọba lẹjọ lori ọrọ na ni? Kini o tun fẹ ba awọn enia sọ lori ọrọ ti o wa ni kotu.

Ṣugbọn awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ko ti sọ bi Dọkita Okpara mbọ wa si Ipinlẹ na mọ tabi yio duro nitori ọrọ ti awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ sọ.

Ohunti Okara ba sọ ni owurọ yi lori ọrọ na ẹo tun ma a gbọ ninu IWE wa.


Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgboṣe Street Lagos Phone 21985
Editor:- TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street, Lagos 20/5/64